# OUNJẸ ÌYÈ
## Johannu 6:22-65
## ẸKỌ 94 – FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Jesu wi fun wọn pe, Emi li onjẹ ìye" (Johannu 6:35).**

### Wiwa Jesu

Lẹyin ti Jesu ti fi iṣu akara marun-un ati ẹja wẹwẹ meji bọ́ ẹgbẹẹdọgbọn (5000) eniyan lọna iyanu, ti O si mu awọn alaisan lara da tan, O rán awọn eniyan lọ. O paṣẹ fun awọn ọmọ-ẹyin lati lọ si iha keji Okun Galili ṣiwaju Rẹ̀, nigba ti Oun duro lati gbadura. Bi igbi ati afẹfẹ ti bẹrẹ si i daamu ọkọ ti awọn ọmọ-ẹyin wà ninu rẹ̀. Jesu bẹrẹ si rin lori omi lọ ba wọn. O fi opin si ibẹru wọn ati rirú omi okun.

Ni ọjọ keji awọn eniyan naa pada lati wá Jesu. Awọn ọmọ-ẹyin ri ba ọkọ kan naa ti o wa lọ, ṣugbọn Jesu duro lẹyin lati gbadura. Awọn eniyan naa ko mọ pe Jesu ti lọ ba awọn ọmọ-ẹyin ati pe O wà ni apa keji okun. Awọn ọkọ miiran ti Tiberia wá; nigba ti awọn eniyan naa kò ri Jesu, wọn ba ọkọ lọ si Kapernaumu, ibugbe Jesu (Matteu 4:13).

Nigba ti wọn ri Jesu, wọn beere bi O ti ṣe de ibẹ, nigba ti awọn ọmọ-ẹyin ti wọ ọkọ kan ṣoṣo ti o wà lọ, ti ọna si jìn ju lati rin yika okun naa. Bi o tilẹ jẹ pe wọn ti ri iṣẹ iyanu ti Jesu ṣe ni ọjọ ti o kọja, wọn ko i ti mọ bi agbara Rẹ ti tó.

Ni akoko yii ki i ṣe ounjẹ ti ara nikan ni Jesu fi bọ́ awọn eniyan naa, ṣugbọn O bẹrẹ si waasu fun wọn, O si n fun wọn ni ounjẹ ti ẹmi. O mọ idi rẹ̀ ti wọn fi tẹle Oun. Ki i ṣe nitori Ọmọ Ọlọrun ni Oun i ṣe. Ki i ṣe nitori wọn ri iṣẹ iyanu ti O ṣe, tabi pe wọn gba A gbọ, ṣugbọn nitori O ti bọ́ wọn yó, eyi si ti tẹ́ wọn lọrun.

### Ounjẹ Ayeraye

Jesu bá wọn wi nitori kiki ohun ti ara ni wọn n rò, O si sọ fun wọn pe ki wọn lo akókò wọn lati ṣiṣẹ fun ohun ti ẹmi, eyi ti yoo wà titi ayé. Ni ojoojumọ ni ọkunrin ati obinrin n ṣiṣẹ fun ohun ti aye yii eyi ti yoo bajẹ. Wọn a maa lo ọpọlọpọ akoko fun gbigbin, rira ati pipese ounjẹ, eyi ti ki i duro pẹ. Wọn o jẹ ẹ, yoo si tán lai pẹ, tabi ki o bajẹ. Fun igba diẹ ni a le pa ounjẹ mọ nipa fifi ohun ti ko ni jẹ ki o bajẹ si i, nipa sisé e mọ́ inu agolo tabi nipa mimu ki o wà ni tutu bi yìnyín. A tilẹ sọ fun wa pe ninu gbogbo eto pipamọ yii, ọpọlọpọ anfaani ni o wà ninu rẹ̀ ni o maa n sọnu. Bakan naa ni awọn ti o ba n fi oye eniyan yí ounjẹ ti ẹmi pada maa n ba anfaani ti o wà ninu rẹ̀ jẹ́ fun awọn eniyan. A n fẹ Bibeli gẹgẹ bi Ọlọrun ti fi i fun ni, a n fẹ ẹ gẹgẹ bi o ti jade lati ipilẹṣẹ wá, lai si alaye ti eniyan ninu rẹ̀.

Jesu n sọrọ nipa ounjẹ ẹmi eyi ti ki i tan ti ko si le bajẹ bi o ti wu ki o pẹ tó. Abu-ibu-tan ni. Lati ọpọlọpọ ọdun titi di isisiyii ni awọn eniyan ti tọ ọ wò, ti wọn si n jẹ ninu rẹ̀ lọpọlọpọ, ti wọn si ti wa laaye nipa ti ẹmi, sibẹ ko dinku si bi o ti tó tẹlẹtẹlẹ. Ki i ṣe kiki pe Ọrọ Ọlọrun wà pẹ titi nikan ṣugbọn a maa fi iyè fun awọn ti o ba n jẹ ninu rẹ̀. "Nitori Ọlọrun fẹ araiye tobẽ gẹ, ti o fi Ọmọ bibi rẹ̀ kanṣoṣo funni, ki ẹnikẹni ti o ba gbà a gbọ́ má ba ṣegbé, ṣugbọn ki o le ni ìye ainipẹkun" (Johannu 3:16).

### Lati Ṣe Iṣẹ Ọlọrun

Jesu wi pe eniyan kò gbọdọ ṣiṣẹ fun kiki ounjẹ ti ara nikan, ṣugbọn ki wọn ṣiṣẹ lati gba ounjẹ ti ẹmi. "Ẹ tète mã wá ijọba Ọlọrun na" (Matteu 6:33). Awọn eniyan naa beere ohun ti awọn o ṣe, ki wọn ba le ṣe iṣẹ Ọlọrun. Jesu dá wọn lohun pe ẹni ti o n fẹ ṣe iṣẹ Ọlọrun ni lati gba Ẹni ti Ọlọrun rán gbọ́. Wo bi awọn ẹlomiran ti ṣina ninu ero wọn tó, nitori ko ṣe e ṣe fun ẹnikẹni lati le ti ipasẹ iṣẹ ọwọ ara rẹ̀ ri oju rere Ọlọrun, tabi ki o wọ Ọrun. Iye owo kan naa ni olukuluku ni lati san lati le wọle. "Nitori ore-ọfẹ li a ti fi gbà nyin là nipa igbagbọ́; ati eyini kì iṣe ti ẹnyin tikaranyin: ẹ̀bun Ọlọrun ni: ki iṣe nipa iṣẹ, ki ẹnikẹni má bã ṣogo" (Efesu 2:8, 9).

### Awọn Ti N Wá Ami

Awọn eniyan naa mọ pe awọn ni lati gba Jesu gbọ́, ṣugbọn wọn beere ami kan ti wọn o fi ni idaniloju pe Oun ni Ẹni ti Ọlọrun rán. Ki ni Jesu i ba tun ṣe ju eyi ti O ti ṣe lọ? O ti wo olokunrun sàn, O ti mú igbi dakẹ rọrọ, O si ti fi ounjẹ fun awọn ọpọ eniyan loju wọn. Ta ni ẹni ti o tun le ṣe iru nnkan wọnyii bi kò ṣe Ọmọ Ọlọrun? Awọn miiran lode oni, a maa beere ami lọwọ Jesu, nigba ti ohun gbogbo ti o yi wọn ka jẹ ijẹri si iṣẹ iyanu. Onigbagbọ kọọkan jẹ ami agbara Jesu, ẹri kọọkan jẹ àmi iṣẹ iyanu Rẹ̀. Ọpọlọpọ ami ti o wà bi awọn eniyan ba yàn lati ri wọn, ki wọn si gbà wọn gbọ, lode oni ati ni igba ti Jesu n ṣe iṣẹ iranṣẹ Rẹ̀ ni aye. Ọpọlọpọ ni o n fẹ lati gba iranlọwọ ti ara lọdọ Ọlọrun, ṣugbọn diẹ ni awọn eniyan ti wọn n fẹ lati ri ibukun ti ẹmi gbà.

**Manna ni Aginju**

Awọn ọpọ eniyan naa ranti bi Jesu ti bọ́ wọn ni ọjọ kẹta sẹyin; lai si aniani wọn tun n foju sọna fun akara ati ẹja si i; nitori wọn sọ fun Jesu pe a fi ounjẹ bọ́ awọn Ọmọ Israẹli ni aginju (Ẹksodu 16:12-16); manna ni a fi fun wọn, ounjẹ Ọrun (Orin Dafidi 78:24,25). Awọn eniyan wọnyii ti kuna lati mọ itumọ manna yii. Gbogbo nnkan ti wọn saa n fẹ ni ounjẹ ti ara lati tán ebi ti n pa ikùn wọn, ṣugbọn wọn ṣe alaibikita nipa ounjẹ ti ẹmi.

**Jesu, Manna Tootọ**

Bi Jesu ti n ba awọn eniyan naa sọrọ, O fihan fun wọn dajudaju ohun ti Oun jẹ fun wọn, ati ohun ti Oun jẹ fun awa ti igba isisiyii pẹlu. Ki i ṣe Mose ni o fun awọn Ọmọ Israẹli ni manna, ṣugbọn Ọlọrun ni O rán an sọkalẹ. Ṣugbọn manna yii jẹ́ apẹẹrẹ ounjẹ tootọ ti Ọlọrun rán (Johannu 6:32). Awọn Ọmọ Israẹli ti jẹ manna yii ṣugbọn nigba ti akoko to wọn kú. Ọlọrun ni ounjẹ ti o sàn ju eyi lọ nisisiyii, nitori Manna tootọ ti Ọrun a maa fun ni ni iye – iye nipa ti ẹmi (ẹsẹ 49, 40).

Awọn eniyan naa beere fun ninu ounjẹ naa ti o n fun ni ni iyè. Nigba naa ni Jesu sọ fun wọn pe Oun tikara Oun ni Manna tootọ, Ounjẹ Ọrun, tabi Ounjẹ ẹmi (ẹsẹ 51). Kò yé wọn. Ọmọ gbẹnagbẹna nì kọ́ ni eyi? Ki ni ṣe ti O wi pe Ọrun ni Oun ti wá? O ti sọ pe ara Oun ni ounjẹ naa. Bawo ni wọn ṣe le jẹ ara Rẹ̀? eyi ni ibeere wọn.

**A Gbọdọ Ní Ọrọ Naa**

Jesu n ba wọn sọ siwaju si i nipa ounjẹ fun ọkan. Ninu Johannu 1:14, a ka pe "Ọ̀rọ na si di ara, on si mba wa gbe." A n pe Bibeli ni Ọrọ Ọlọrun. Jesu wi fun wọn pe Ọrọ ti Oun n sọ fun wọn ẹmi ni, iye si ni (Johannu 6|:63).

Bi awa o ba jẹ ara Jesu ki a si mu Ẹjẹ Rẹ̀, a ni lati gba gbogbo Ọrọ Ọlọrun sinu wa, eyi ni Bibeli. A ni lati gba a gbọ ki a si gbe igbesi-ayé ti o palaṣẹ. Ounjẹ ti ara ti a n jẹ a maa fun wa ni okun a si maa mu ki a dàgba. Bibeli a maa ṣe bakan naa fun wa nipa ti ẹmi. Ki eniyan ba le ni iyè ninu ẹmi o ni lati gba Bibeli gbọ́, ki o ṣe ohun ti o palaṣẹ, ki o si jẹ ki o di ara fun oun. Nigba ti a ba n jẹ ounjẹ ti ara, a o jẹ ẹ lẹnu wa, a o si jẹ ki o lọ sinu ara, a si di ara wa. Eniyan le maa wo tabili ti o kun fun ounjẹ, tabi ki o maa gbe e lọwọ ara rẹ̀ kiri, ṣugbọn bi ko ba di igba ti o ba jẹ ounjẹ naa, kò le ṣe anfaani kan fun un. Ebi le pa a ku nipa kikuna lati jẹ ẹ tabi nipa ṣiṣe aibikita lati jẹun. Bakan naa ni nipa ti ẹmi, a ni lati jẹ ki Ọrọ Ọlọrun di apa kan ara wa, ki a ba le ri anfaani gbà lati inu rẹ̀ wá. Ounjẹ naa (Bibeli) ni a ti pese silẹ fun wa. Eniyan le duro, ki o maa wò -- òkú nipa ti ẹmi – nigba ti awọn ẹlomiran n ri igbala. O tilẹ le maa gbe Ọrọ naa kiri, ki o má si ni iye ainipẹkun (ẹsẹ 53, 58). A ni lati gbọran si aṣẹ Bibeli bi a ba fẹ lati pa igbala wa mọ́ ti a ba si n fẹ lati ri igbala. Eniyan a maa wà laaye nipa jijẹ ounjẹ, nipa ti ẹmi ati nipa ri ara (ẹsẹ 57).

Gẹgẹ bi awọn Ọmọ Israẹli ti maa n kó manna ni orowurọ bẹẹ gẹgẹ ni Onigbagbọ ni lati jẹun lati inu Bibeli lojoojumọ lati fun un ni agbara ati lati mu un wà laaye nipa ti ẹmi. Bi eniyan ko ba jẹ ounjẹ ti ara ni ọjọ kan, aarẹ̀ yoo mu un ko si ni le daraya daradara. Bẹẹ gẹgẹ, Onigbagbọ ni lati jẹun lojoojumọ. Kò si ẹni ti o n fẹ lati jẹ alaarẹ̀ ninu igbagbọ tabi alaisan ninu igbagbọ.

**Oku nipa ti Ẹmi**

Nigba ti Jesu wi pe a fi bi o ba jẹ ara Rẹ̀ ki o si mu Ẹjẹ Rẹ̀, iwọ ko ni iye ninu rẹ (Johannu 6:53), ohun ti O n sọ ni pe iwọ jẹ oku nipa ti ẹmi. Awọn ti o n dẹṣẹ jẹ oku nipa ti ẹmi (1 Timoteu 5:6); ṣugbọn nigba ti wọn ba gbadura fun idariji ti wọn si gba Ọlọrun gbọ́, wọn ko tun n ṣe oku mọ́ ṣugbọn wọn di alaayè (Efesu 2:1; Kolosse 2:13).

Laaarin awọn ti o gbọ nigba ti Jesu wi pe, "Emi li onjẹ ìye," awọn miiran ninu wọn wi pe ọrọ ti o le ni eyi pe awọn ko le ṣe gẹgẹ bi O ti ni ki wọn ṣe. Awọn miiran ti wọn n pe ara wọn ni ọmọ-ẹyin Rẹ̀ tilẹ n kùn si ọrọ Rẹ̀. Ki ẹnikẹni ti o ka ẹkọ yii má ṣe dabi wọn, ṣugbọn ki o gbọran si ọrọ wọnyii: "Jí, iwọ ẹniti o sùn, si jinde kuro ninu okú, Kristi yio si fun ọ ni imọlẹ" (Efesu 5:14).

## AWỌN IBEERE

1. Ta ni Ounjẹ Iyè?
2. Ki ni ṣe ti a pe E ni Ounjẹ Iyè?
3. Lati ibo ni a ti rán Ounjẹ iyè naa wá?
4. Bawo ni a ṣe le ri I gba?
5. Ki ni Ounjẹ Iye naa yoo ṣe fun wa?
6. Igba meloo ni a gbọdọ maa jẹ ẹ?
7. Ki ni ṣẹlẹ si awọn ti o kuna lati jẹ Ounjẹ Iye yii?